# ODOMOKUNRIN KAN JA SINU ODO, O DI AWATI




ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO




VOL. IX No. 589. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 28, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

## Ọdomokunrin Kan Ja Sinu Odo, O Di Awati

EKO. Ibosi Oro ol ẹgba wa o, ni ḷigbe ti o tan kari oke Olowogbowo ni aṣalẹ ọjọ Alaruba Sept 25th 1957, nigbati irohin de etigbọ awọn obi ọdọmọkunrin kan ti ẹsẹ rẹ ṣeṣi ta sere lati inu ọkọ ero ti o nko awọn oṣiṣẹ lọ si Apapa.

Ọdọmọkunrin ti o ṣe kongẹ agbako iku ojiji yi ni orukọ rẹ njẹ Suraju, ti o jade lati ile rẹ lọ ibi iṣẹ, ounjẹ ọjọ rẹ pẹlu ara ile, ti o fi iya ati awọn obi rẹ silẹ, lati lọ wa onjẹ ojo rẹ ṣugbọn alọ rẹ ni awọn ri awọn ko ri abọ rẹ mọ.

Irufẹ ajalu jamba iku ojiji bawọnyi larin ọdọmọkunrin wa jẹ ohun ibanujẹ pupọ fun awọn obi wọn.

A gbọ wipe, ọmọ agbede ala kan ni elogbe na jẹ ni Olowogbowo. Ọba kofi ori ji oku na, ki o si tẹ si afẹfẹ rere.




THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
87, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO; BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbeniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olabanmi Olasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Minister lo wo awon eranko



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni ọlọla Alhadji Isa Kaita, oloye ilu Katsina, pẹlu iyawo rẹ, nigbati awọn lọ bẹ ọgba awọn ẹranko wo nilu Oyinbo. Hadji Isa Kaita yi lo dakan lọ ṣe aṣoju ninu igbimọ apero [illegible] ti awọn ṣe ni Cambridge ninu oṣu August ni [illegible].

Ohun iyanu ti nwọn ri ninu ọgba awọn ẹranko [illegible] na ni awọn ẹiyẹ kan to dabi Pẹpẹyẹ odo ṣugbọn [illegible] o nrin ni iduro. Awọn ẹiyẹ na ko nse fun enia, [illegible] wọn dabi ẹsẹ ajapa okun.

# Lagos Race Club
# OCTOBER MEETING

## Saturday 5th, Monday 7th, Saturdays 12th, 19th and 26th Oct. 1957.

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5, 55 p.m. |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 8 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 9 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 10 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 11 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 12 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 13 | Five Furlongs Handicap Top Division | 5, 55 p.m. |
| RACE No, 14 | Five Furlongs Handicap Top Division "A" | 6. 30 p.m. |

### THIRD DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 15 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 16 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35. p.m. |
| RACE No. 17 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 18 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 19 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 20 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 21 | Seven Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

### FOURTH DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 22 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 23 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 24 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 25 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 26 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 27 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.55 p.m. |
| RACE No. 28 | VICE CHAIRMAN'S PRIZE Ten Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

### FIFTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 29 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No, 30 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 31 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No, 32 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No, 33 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No, 34 | Nine Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No, 35 | Nine Furlongs Top Division "A" | 6, 30 p.m. |


# Ebo Tabi Etutu

Ẹbọ tabi etutu tabi Saraa jẹ nkan ti o jade ni sakani ẹni lati fi ra ẹmi, alafia, ati idẹra ẹni pada.

Ohun ribi-ribi ni etutu jẹ. Kiriyo mọ ọ, Imale mọ ọ, Oyinbo mọ ọ, bẹni awọn Aborișa mọ pẹlu.

Ọkan ninu awọn etutu ti gbogbo awọn ti a daruko nwọnyi nșe, ni etutu ikomọjade, diẹ enia gbagbọ pe ọjọ kẹjọ ti ọmọ dele aiye ni nwọn nfun ni orukọ. Kiriyo ni etutu tirẹ, Imale ni tirẹ, Aborișa ni tirẹ, awọn oyinbo ni pẹlu.

Ni ọjọ yi, ọpọ enia lo ni etutu ti o nșe nidile rẹ. Șugbọn awọn ẹlomiran ko ni etutu idile șugbọn nitori ti o ti jẹ așa awọn baba nla wa lati ma șe bẹ on na ti ni igbagbọ pe bẹ lo yẹ ki on șe.

Ni ilẹ ilẹ Yoruba, enia ko le ṣisẹ meji ki o to kan ẹbọ nibiti nwọn gbe si, iru orin yi pọ larin awọn ọmọ ilewe. Nigbati nwọn ba nlọ lede ti nwọn si lọ șe konge ẹbọ kan sẹpẹtẹ nibiti nwọn gbe si, lọsẹkanna, orin yi ni nwọn ma nkọ wipe.

Ẹbọ ẹlẹbọ pada lẹhin mi,
Ọmọ Ọlọrun tẹle mi lẹhin,

igbagbọ wọn ni pe, bi nwọn ba ti kọ orin na, buburu ẹbọ na ko ni le ba wọn dele.


## Egbogi Iyagbe Ti o Dara

O njẹki enia lagbara, ki o si ni alafia nigba gbogbo

## "HERBALAX-NDF"

Egbogi yi a ma jẹki enia gbọnsẹ wọrọwọrọ, o nfọ inu mọ, ko si lewu o ntun ọjẹ ẹnia șe pẹlu.

x O jẹ egbogi kan ti o dara fun igbọnsẹ, ko si ni ko enia ninu.

x O nwo gbogbo arun inu san bi Ẹsanri, Igufẹ, Airi oron sun, tabi IȘAKA, Jẹdi-jẹdi, tabi Iju.

x Ohun pataki lo jẹ lati mojuto airi igbọnsẹ șe ki a si pana rẹ.

Tete lọ ra tirẹ loni, afara ko si. A ma nfun awọn ti o ba ra pupọ ni iṣọwo. Ẹniti o nta a ni :-

**French Medicine Stores,**

18, Breadfruit Street, Lagos. Phone 23264.



## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun German to șeșe de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO**

**BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.




# Ero Asise

Bi eni kan ba şeşi şe aşişe kan ti o ba şakiyesi wipe aşişe ni on şeyi ko si fe ki on tun şe aşişe iru rẹ mọ ki o wi bayi si igun mererin aiye wipe.

ỌBỌ NGB'ỌBỌ G'ỌBỌ

Ọrọ yi fere jọ ọrọ yẹyẹ lo/u eniti ko mọ kan o si le mọọ si ọrọ yeye ti ọmọde fi ngere.

O ye ki enia ro o wo kini fa sababi gbolohun yi ti awọn ọmọde fi nşe ere bayi ?.

Bi enia ba le pe gbolohun yi nigba mẹrin laişi i pe ko tun ni şe aşişe bẹ mọ.

K. O. K.
Science Master

## Oloye Jibowu di adajo agba

Ijoba ti ro si eto lati gbe Oloye Jibowu ga si ipo adajo kotu giga nilu Eko, on si ni enia dudu nile Nigeria ti a koko gbe si iru ipo na.

Alhadji Jubril Martins ti o nse asiwaju ninu awọn awujọ Amofin ile Nigeria rohin Oloye Jibowu latigba ti o ti bere işe Amofin ki o to wa di adajọ kekere tebe ki o to wa de ipo yi o si rohin bi o ti je ilọsiwaju fun wa si Ominira ati idagbasoke ni ile wa ninu ominira O ye ki inu wa madun.

# Isipaiya oro die nipa Eko

Iwa gbogbo ti a nba nilẹ Yoruba loni jẹ awọn aşa ti a ba lọwọ awọn aşiwaju wa bi baba, ẹgbọn ati ọrẹ, awọn aşa na si jẹ eyiti nwọn mabọ lati oko ireke (Brazil)

Niwọn ọdun 1910 si ọdun 1920, awọn Olotu ile ẹkọ şe iwe kekere kan nigbana ti a npe ni Ẹkọ nipa iwa (Moral Instruction). Ninu iwe yi, ni a şe alaye oniruru iwa si ati ohun ti o le tidi rẹ hu jade fun enitI o ba nhu iru iwa bẹ. Iwe yi jẹ orişirişi; fun ọmọ onIwe kini, oniwe keji, ẹkẹta, ẹkẹrin ẹkarun.

Awọn Olotu Ẹkọ yan asiko pataki fun ẹkọ nipa iwa yi; igba mẹta ni nwọn nşe e lọsẹ. Bi o ti lẹ jẹ wipe awọn ọmẹ akẹkọ ko le ka awọn ọrọ inu iwe na, ki nwọn si gbọ agbẹye rẹ dara - dara, ati fi aşẹ fun awọn oluko lati pe awọn ọmọ akẹkọ joko, ki nwọn şiwe tiwọn ki oluko ma ka a ki nwọn ma gbọ. ki o si ma şe itumọ rẹ fun wọn li ede Yoruba.

Lasiko ti awi yi, ọpọlọpọ awọn ọmọ ilewe lo ni ọwọ ti nwọn si ntẹriba fun agba, şugbọn lati gba ti nwọn ti yọ iru iwe ba yi kuro ninu iwe Ẹkọ, nigbana ni afojudi ti gbodekan. Ẹ gbọ biolorin Ẹgba ti nwọn npe ni Aribilọşo ti nkọrin - ekute ti sẹ nipa awọn ọmọ alaiberan:—

Alaigbọran, abi eti le koko bi awọ erin;
Abi-ikọ, afọ - igbọ, Ode lo ti nkọgbọn walc,
Angbadiẹ lọwọ ika, o l'onfẹ r'atitan lo jẹ
Adiẹ ko mọ p'ohun pupọ lo farajo kokoro;
Awọn lasni, şebe, Gbagba-fufu jọ kokoro;
Akerekere abiya nibadi farajọ kokoro;
Aşa nkerẹgbẹ nitori oşlo ọmọ adiẹ ni atitan,
Agbere nigbayan to fẹ bọ sagbo Adiẹ jo.
Agbere ni Şigidi to fẹ bọ sinu ojo lati wẹ;
Alaigbọran nwọn ngẹ lọwọ o mbọ oruka;
Ma şe e ile aiye l'ongbe,
Bi a ba şe e nkọ ? o mbọ lọna ẹrun

# Esin Oba Fe Sure Ije



Eniti[illegible]a nwo ni apa osi yi ninu aworan ni Ọba Obinrin ilu Gesi ti o fi ọwọ gba esin re ni imu pepe lasiko, ti nwọn wa mu esin na lati lọ sure ije ni ibikan ti nwọn npe ni Ascot, Orukọ ti nwọn npe esin na ni Aureole. Ere ti esin na fe sa ni ere ije ti Ọba George kefa ati Ọba Obinrin Elisabeti ni esin na fe sa.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. IX. NO. 539. LAGOS, SATURDAY SEPT. 28. 1957

# Ero Gbogbo Lori Sile

Ohun ti a le fiwe owo laiye yi ni ẹjẹ ara enia tabi tani ko mọ wipe ẹjẹ ara enia l'omu enia dagba ti o si nfun enia ni alafia, bẹgẹgẹ ni owo ri. Awọn ajisọdidun lọrọ ni o sọ wipe "ẹkọ gbe'ni niyi, ẹje gbe'ni ga gogoro".

Awọn ti o ṣi Ṣọbu ọja oniyebiye, kini awọn nwa? Owo. Awọn oṣiṣẹ ọba ati oṣiṣẹ awọn Oniṣowo, kini awọn nwa? Owo. Gomina ti o fi ilu rẹ sile bi iwọn ẹgba-gbeje ibusọ kilo nwa? Owo. Awọn akọwe, awọn agb'ẹjọro, awọn Onidajọ tofi d'ori awọn aleru ti o kakiri ilu lati ru ẹru, kini awọn nwa? Owo. Bẹni owo jẹ ẹjẹ ara olukuluku ẹda enia l'ode aiye yi, njẹ a le sọ wipe ẹjẹ owo nsan tara lara ẹnikẹni bi?

Agbẹdọ! eyi ko le bẹ rara paapa l'ode aiye wa oni yi, ti o jẹ wipe Oniru nke, Oniyọ nke, Onisọbu ti o ko ẹru ọja Ogidinleje owo jọ nke tantan fun aita ọja tabi kilo tun ku? ohunkohun ti enia le ni l'ode aiye yi, ti ko ba ni Owo pẹlu, jaburata ni. Nitorina, adura wa niki Ọlọrun Olodumare maṣe fi owo gbẹhin fun wa ninu ohungbogbo. Amin.

## ANFE ASOJU

A nfẹ Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofẹ lati fi kun awọn Asoju wa ni awọn ilu ti a darukọ ni isalẹ wọnyi:-

Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ijẹbu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kọwe si Olotu Iwe Irohin Ofẹ, 28, Kosoko St, Lagos.



## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ototu. Ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko chie. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


# Orisi Ero Asoro-magbesi Ti O Tun Sese De Niyi



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni O. Davies Ọdunsi ti o wa silu Oyinbo lati agbegbe Iwọ-Orun ilẹ Nigeria, on ni ẹniti o nlo ẹrọ asọrọ magbesi kekere kan, ti enia le koda sinu apo yi, lasiko ti nwọn nṣe ajọdun kẹrinlelogun ti ẹrọ asọrọ-magbesi bẹrẹ (Radio) Ọgbẹni Siemens Edison lo ṣe ẹrọ na.

Ko sibiti enia le yi ẹrọ na si ti ko ni gbọ ọrọ ohun ti awọn nṣe nilu na, o le gbọ ọrọ ilu Eko, ti Amẹrika tilu Oyinbo ati ibikibi.

# Alapara Ibadan Nki Yin o

### OKE FỌKỌ IBADAN.

Wọn ni ọmọde ko gbọdọ sọ itan agbalagba; bẹni ṣugbọn Ọlọrun ma jẹ ki awọn ọmọde ti o mọ itan tan lori ilẹ aiye. Ọrọ emi Alapara di ori Alaiyeluwa Ọba Ladapọ Ademọla (Ọba Alake) nilu Abẹokuta "Ọmọ Erin jogun Ọla", mo juba o. Bi ekolo ba juba baba rẹ, ilẹ a lanu fun u. Oke Olumọ, Oke-Ibadan-Oke loke njẹ, ko si kekere oke. Awe, oke ma ṣoro gun, Oke Olorenbo wa, bẹni oke Ibẹpẹ-Iru oke bẹ kọ ni a nwi.

Oke Olumọ ti mo gun ni aipẹ yi, Mọkka (Mecca) lo jẹ fun mi. O wa mu mi niran oke ti mo ba wọn gun ni Ile-Ifẹ nigbati Alaiyeluwa Ọba Ọni nṣe ọdun "Ọlọjọ" pẹlu awọn agba Ifẹ. Alalẹ'fẹ ngbọ; ọdun ni ọdun "Ọlọjọ" ni Ile-Ifẹ. Oduduwa jẹ ki nle ba wọn ṣe eyiti nbọ yi o.

### KABIYESI ỌBA ALAKE

Kabiyesi Ọba Alake ade a pẹ lori bata a pẹ lẹsẹ, ṣugbọn itọju ilu Ẹgba dọwọ re. Enyin ọmọ Ẹgba, mo ti de Abeokuta tipe a fi eyiti mo wa ni aipe yi lati wa ba wọn gun Oke Olumọ. Mo lọ si ilewe ni Oke Ẹgunya ri, mo wa pari iwe akọpọ mi ni Oke Igbehin. Iyen mu wa mọ die ninu ọrọ awọn ara Abeokuta (ABE-KETA ni awọn Ẹgba

(Wo yoku loju ewe karun)

## Alapara Ibadan

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

ehin odi npe). Ẹgba mo juba o.

Ki ilaju to jade kakiri gbogbo ilẹ Naijiria ni awọn Ẹgba ti nṣe ilu ara wọn, otẹ ati tembelekun Ogun Ijemọ lo mu alupaida de. Ẹgba lo kọ gba owobede alle yi. Wọn a si ma lo fun Ire ile wọn.

Mo ripe tembelekun ogun Ijemọ ati rikiṣi ogun Adubi ṣi wa nilu Ẹgba nisisiyi, Ko nṣe lowọ awọn ọba ilu, bikoṣe lọwọ awọn Olowo Ake, bọkinni Owu aladire Itoku onigbagbe Isabọ oni ilu Ijaiye elelubọ Iberekodo adajọ Gbagura ati sanmọri OkeỌna-papa lọwọ emi Alapara Ibadan ti mo wọ ewu ti mo wa kọ oju re ehin. Ko nṣe ejọ mi bikokoṣe Alabawi ti ko si lọdọ mi nigbata mo nwọ.

Ọrọ pọ ti mo fe ba enyin ọmọ egba sọ l'ọkunrin l'obinrin, ṣugbọn mo fe lọ ba Ọba Alake ṣe ajọyọ ọdun metadinlogojo ti o ti bere oye re ni ọse ti a fe bọ si.

Alapara ni ki e ba on gbe orin:-

A ni ka ṣerepọ o
Wọnkuwọ
Ka ṣerepọ o
Wọnkuwọ".

Ẹyin ọmọ Ẹgba ẹ ṣe ere pọ o. Mo ni enyin ọmọ Ẹgba e je k'a ṣe ere pọ.

### TINUBU ṢUBUỌLA ATI KUTI

Tinubu nikan ni nko gbọnjẹ ba nigbati mo nṣe Sanmọri ni ilu Ẹgba. Mo mọ ọmọ Ẹgbẹron-gbe, Ṣubuọle; mo ri arabinrin wa Ṣubuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe ki o to ku ni Ibi[?] a npe ni Idi-Aba ni Abẹokuta. Iya Ọlọla ti di ologbe ṣugbọn o ṣe gudugudu meje nina ogun Adubi nilu Abẹokuta nigbati awọn ṣoja ko jẹ ki Ẹgba ile ati toko mi O yẹ k'a ṣe iboji Ṣubuọla si Idi-Aba.

Iya wa Tinubu nkọ ewo la ṣe fun? Ẹnyin ara Owu, ọrọ yi di ori yin. Owu ti a wuno pe. Wọn ni ẹ ki gba igbakugba. Bẹni lorile Owu, bẹni ni Ile-Ifẹ, bẹna si ni ni ABEOKUTA.

Kutu-kata pin. Sugbọn ọna Ẹgba ko pin. Ẹ jẹ ki a ṣe oko Tinubu, Tinubu ṣe pupọ fun Ẹgba. Burọda Kuti mo ngbọ ohun rẹ; oku ẹni-rere ko sun bọrọ. Alapara nki yin o, oku ẹni-rere ko sun bọrọ, Ẹgba, o di ọwọ yin o.

## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o bafe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sosi Aguda Nilu Ibadan.**




Awon gbajumo enia gba pe ....



Eyi ni lati je oti "Star Beer!" O soro lati si iru oti lager atata bẹẹ mọ. Iri rẹ didara ati ti tutu ti ntawanin-wanin jẹ ami bia ti o dara julọ—Star si ni!
Agb'ọti—fun mi ni Star Beer mẹta si!!

OTI
STAR
l'o je eyiti o dara ju!



Beni Sammy Sparkle wi.



OTI BIA ti o dara ju nfe ohun ti o tun ... eelo atata lo—o nfe ogbon ati imo. O kun eelo oti ati oka bali ti o dara julo ti nwon mu wa lati ilu okere ni nwon fi se e. Awon ologbon ponti-ponti ti o wa lati ilu Oyinbo ni o nse Star Beer olokiki na. O gba iyi pe on ni asiwaju oti lager ti nwon fi Igo ro ninu Idije British Empire ati Commonwealth ti nwon se ninu odun 1954, Oti ti o gbadun ju ti o tutu lenu ti o si ni itelorun gidigidi ni.

# Ajakale arun ti odun 1918

Awọn ara ilu Eko, ko ni gbagbe oṣu October 1918, lailai. Ha! lọjọ buru ku ki eṣu gba omi mu. Ninu oṣu yi ni ajakalẹ arun kan bẹ silẹ nilu Eko eyiti nwọn npe ni Ayọkẹlẹ. Ko si yẹ ki a gbagbe itan bayi. Oṣu dudu lo yẹ ki a ma pe oṣu ọdun na.

Gẹgẹbi Influenza ti o wa lode yi ti nṣe, bẹni o nṣe nigbana ko si ile kan ti enia kan tabi meji ko ku. Yala olowo, ọlọrọ, talaka akuṣẹ, ọmọde tabi agba ti ko ṣe ọfọ ara, ẹbi, ibatan, ọrẹ, aladugbo ọmọ iya tabi baba lọkunrin ati lobinrin, ko si ẹni ti ajakalẹ arun na ko fi ọwọ kan.

Nigbati iku na pọ, arọ mu awọn kapinta ti o nkan posi, agara mu awọn ti o ngbẹ iboji oku ko si enia lati sinku mọ, nṣe ni awọn enia miran nlọ gbe oku junu sinu itẹ oku, nwọn o si pada sile.

Ko si ẹnikan ti o roju lọ ki ẹni keji ku ọfọ. Enia ko roju kirun si oku lara, ko si ẹniti ti o le gbọ oku wọ ṣọṣi lati ri enia ba wa gbe oku kan lọ si itẹ oku, iṣoro pupọ ni.

Nigbati iku na papọju ẹnikan ko roju gbe oku lọ si tẹ mọ, bi ilẹ ba ṣu, nwọn o lọ gbe oku wọn ju sinu odo ọsa. Bi ẹnikan ba si huko ninu ile kan, nṣe ni iwọ yio gbọ ti gbogbo adugbo na yio gba ikọ, nwọn si ma hukọ lọ bẹ titi lati adugbo kan de ekeji ti ti yio fi de ipẹkun ilu.

Ko si aye lati wọ Mọṣalaṣi lọ, bẹni gbogbo ilẹkun Ṣọṣi ni nwọn ti awọn ọmọ ilewe ko ri aye lọ, oniwasu kan ko le jade. Ẹgbẹ Serafu ko ṣaiti bẹrẹ lakọkọ na.

Ṣiwaju ki ajakalẹ arun yi to de, ijo ni gbogbo ara Eko njo kiri. Lasiko na, larọ ati lalẹ agbara kaka ni iwọ yio fi ri to ogun enia ninu Ṣọṣi awọn enia diẹ lo si nkirun. Lojojumọ ni a nri awọn abami enia larin ilu Eko, ti nwọn o ma wi bayi pe, Ẹrosupiwada nitori ti Ijọba Ọlọrun ku si dẹdẹ. Okunrin ọdẹ kan ti nwọn npe ni Egunjọbi ara Ibadan, agbalagba rẹ ti odidi Ibadan wa si Eko wa sọ ohun ti o ri, o si mu ami wa, ṣugbọn kaka ki nwọn gbọ, ki awọn kede awẹ, nṣe ni nwọn nfi ọdẹ yi kọ'rin ti nwọn njo kakiri ilu.

Lasiko na Ogun wa larin Gẹsi ati Jamani Nigbati o ṣe si irohin de lati oju ogun pe arun kan bẹrẹ larin wọn ti o npa enia bi denge. Lọjọ kẹta rẹ ni arun na de ilu Gẹsi. Kawi kafọ, ọjọ kẹta o de ilu Saro ọjọ kẹta si eyi o de Ghana, Ọjọ kẹta eyi lo de Eko ṣangba fọ agbole miran fẹrẹ di ahoro. A gbọ lẹnu awọn ojọgbọn igba na pe iye awọn enia ti o ku nilu Eko nigbana le ni ọkẹ mẹdọgbọn enia (500,000).

---

## Lehin Ogorun Odun Oku Ojo Martins Sipo Pada

(O bere lati ọsẹ to kọja)

Dady Ojo Martins je enikan to gbajumọ nigba aiye rẹ, enia gigun lo nṣe, o si ṣe lẹgẹ-lẹgẹ. Ni paṣẹ rẹ ni ogunlọgọ awọn ọmọ Ijaiye ṣe de Eko.

Diẹ ninu awọn ẹgbẹ rẹ ni Daddi Layẹni, Kamu-Davies (Capt. Davies) Talwo Olowo, Oloye Akanni, Ọbadina Kakawa, Daddy Ladipọ, ati Ṣita.

Lẹhin ọgọrun ọdun ti Ojo Martins ti ku, ti nwọn ati sin'ku rẹ si oju opopo ita Martin ni nwọn hu oku re jade Ohun ti nwọn ba ninu oku rẹ ni afọku agbari rẹ, ẹdun ara, Owo ẹyọ, ajẹku ẹdọforo ati gbogbo ohun ti o mbẹ ni igba aiye, egungun ọwọ, ti ẹsẹ, ti ẹhin, gbogbo iwọnyi ni nwọn ko papọ sinu posi, nwọn si deda.

Oju gbogbo arọmọdọmọ Ojo Martins lo pe sibẹ, nwọn pa ẹran, nwọn ba obi, ki nwọn to lọ sinku rẹ si ojude Dọkita Maja ni gbangba ita Akanni.

Tẹlẹ-tẹlẹ, Akangbe ni oruko baba ti o bi Martins. Adebayọ lo orukọ ti on paapa njẹ. orukọ Amutọrun wa rẹ lo njẹ Ojo. Nigbati o mu de Brazil, ọkunrin olowo kan ti nwọn npe ni De la Martins lo ra Ojo, eyi nidi re ti awọn Aguda ẹlẹgbẹ rẹ fe npe e ni Ojo Martins

---

## Iku Bolaje

Iludun Otun Oro Anu se mi lati gbo iku iya okawe wa kan ti oruko re nje Serah Olarinke ti o jalaisi ni ojo Jimo ti o bere ninu osu ti a wa yi ni Ile Ajalegbe ni ilu ti a npe ni Iludun, Otun Oro, leti Offa, Gere ti omo iya ologbe yi ti oruko re nje Zakiu Adeoye ti o nse ise owo ni Eko ti ri onise ni o ti mura ti o ti te oko leti on ati opolopo awon ara re pelu ore lati Ebute-Metta, Eko ati Offa lati lo sinku iya oninu're yi.

Isinku na ti a se ni Sosi Iludun, Otun oro dun, o ni arinrin bi omoloku ti nnawo beni awon ebi re na nna lotun-losi.

A ki awon omo oloku na ku asehinde o, Ehin iya na yio dara o.

---

## Enia dudu elere Sinema



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Nortey Engman, on ni omo ile Ghana ti o se ere sinema kan ti nwon npe oruko ra ni Kumasenu to si gba ilu Mogandisu pada kuro lowo ota. Nigbati o si mbe ni omo ilewe ni o ti se ere ti a wi yi. Nisisiyi, o ti dagba, o nko ise ero itewe ninu ise ijoba Ghana.

# Shell kerosine is 3 times better *for Lighting*



1. LONGER LASTING
2. CLEANER BURNING
3. STRONGER FLAME

*All the users of SHELL KEROSINE agree there's none better*



For the brightest light buy SHELL KEROSINE

# Agbegilere ile Nigeria fise han ni London



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni ere obinrin ti o jẹ ove Iyalode nigba aiye rẹ (Obosi) ti ọgbẹni Agbegilere ilẹ Nigeria kan ti nwọn npe ni Felix Idubor gbe nilu Oyinbo ti Ọgbẹni M. T. Mbu ṣe afihan rẹ fun gbogbo aiye ri.

Awọn ere ti a fi ṣe afihan na le ni Ogoji ti imura won si jọ aṣa ilẹ Nigeria Awọn igi ti o lo lati fi gbe awọn ere na ni igi Ẹboni, igi Opepe, igi Abora, igi Iroko ati Arere.

Ọgbẹni Idubor yi lo kan apoti alarabara kan, ninu ey'ti nwọn fi awọn aworan ti a ya ni mere-mere ni akoko igba ti ọba obinrin ilu Oyinbo wa bẹ ilẹ Nigeria wo si, ki a to lọ fi ta ọba na lọrẹ. Apoti na si jọ ọba lojü.

Ọba si paṣe wipe, ki a fi awọn aworan na si bi oju taiye nlọiti gbogbo awọn eniti o ba fẹ mọ nipa ile Nigeria yio ma wo nibẹ, ki awọn le mọ iru awọn enia ti nwọn nlọ ba pade.

## Ilosiwaju Nla Yio Bere Ni Iwo-orun

Irohin ti a gbọ lati ilu Ọba wa ni wipe ilọsiwaju nlanla ni yio bere si sele ni agbegbe ile Iwọ Orun Nigeria.

Awọn onişẹ ẹrọ gbohun-gbohun ti ilẹ yi so pe, nwọn fẹ da ẹrọ yi kan silẹ ni Iwọ Orun, ẹrọ nla kan ni nwọn fẹ gbe kale ni ilu Ibadan, nwọn si ti bere iṣẹ na, ṣugbọn awọn eroja re yoku kotti de.

Nwọn si fẹ kọ ile nlanla kan fun irin iṣe ẹrọ yi nilu Ibadan, aye tibiti awọn o fi ijoko iṣe na si ni nwọn si nwa.

Titi digba ti ao fi pari ile nla na, eyi kekere ti a ṣi nlo lọwọ yi ni ao ma lo.

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe





### ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute-Metta.
Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.


## Obinrin kan Gun ara re pa

EKO. B'o lọ ki o yago fun mi ni ariwo ti a gbọ ni opopo Apọngbọn ni ibẹrẹ ọsẹ yi, nigbati a gbọ wipe ọdọmọbinrin kan ti oruko rẹ njẹ Marian Oni ti o ngbe No. 107, Apọngbọn Street, l'Eko gun are rẹ pa sinu ile

Kini o fa sababi yi ni awọn ọtẹlẹmuyẹ si nwadi lọwọ.

Lọwọ iku gbigbona, Oluwa tere gba wa.

## Rufai Apatira Di Ologbe

EKO. Agbọjugbasu nitti iku sanmọri arẹwa ọdọmọkunrin ologbe Rufai Apatira ni ọjọ Sanday, Sept. 22nd nigbati irohin tan yika igboro Eko. Rufai jẹ ọdọmọkunrin ọlọyaya kan ti a bi ni ile pataki kan nilu Eko, a bi ni Iga Apatira ni Ita Faji o si kọ ẹkọ iwe rẹ ni ilewe C,M.S. Grammar School.

Nigbati o jade ni ilewe, o ṣiṣẹ fun ọjọ pupọ nile iṣẹ U.A.C. ki o to wa bọ si abẹ awọn Oyinbo Elepo (Mobil Oil). Ologbe yi fi aya meji sile ati awọn ọmọ diẹ. Awa Eleti-Ọfẹ fi wosika wa yi ki awọn ẹbi ologbe yi, nwọn ku afẹku o.


## Powo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe



## Lati fun o lokun-inu ati agbara re pada

Lẹhin

AMODI INFLUENSA

lo egbogi

**Hommel's Haematogen**

pẹlu Wara tabi Ọti Waini fun ọsẹ kan tabi meji

A le rira ni Ṣọbu ti awọn nta egbogi ati ni gbogbo ile itaja

ALAKOSO EGBOGI NA NI-

**ALBAN PHARMACY LTD.**
2, VICTORIA STREET,
Lagos.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box 487 Lagos Phone 23579